# ELETI ỌFẸ

'A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ'

VOL XIV NO 914 LAGOS SATURDAY MARCH 28—APRIL 3 1964 KỌBỌ KEJI 2D)


## OLOTU IJOBA FESE FE !

# Omi Le Awon Asofin Jade Ni Ile Igbimo

BENNI CITY— A gẹgẹ tẹsẹ kan bọ odo omi gbe e lọ ni ọrọ ipade ile ile igbimọ awọn aṣofin Ijọba agbedemeji Iwọ Orun (Mid-West) ti nwọn pejọ ẹni ijẹta lati jiroro owo ti nwọn yio na ni arin odun kan ti alagbalugbu omi ojo ya wọle o le wọn kuro ni ile igbimọ na lọgan.

A gbọ wipe ere ni awada ni gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ Alakukọ ti nwọ jẹ opomulero Ijọba tuntun na It bẹrẹ! salọ sọdọ awọn alatako ti omi ko ti ya de, wara were nwọn ti npalẹmọ gbogbo eni olowo iyebiye ti nwọn tẹ silẹ, Oloye Dennis Osadebay, Olotu Ijọba tuntun na paapa ba fi ẹsẹ fẹ; gbogbo iwe ti nwọn fẹ fi jiroro owo ti nwọn yio na na ni ojo bajẹ patapata.

## Oselu Kan Bebe Wipe Ki Nwon Da Oloye Awolowo Sile

EKO— Ni ile igbimọ awọn aṣofin l'Eko ni ana ni a gbọ irohin kan wipe Ọgbẹni E A Mordi ọkan ninu awọn oṣelu ọmọ ẹgbẹ Alakukọ (NCNC) dide ti o nfi bi ọgbọn iṣẹju bẹbẹ lọdọ Ijọba wipe awọn fi oju anu wo Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ, Olori ẹgbẹ Alatako ti nwọn ju sẹwọn ọdun mẹwa lori wipe awọn dite si Ijọba, ki nwọn da a silẹ.

Ọgbẹni Mordi ni bi awọn ti nwọn nṣe alakoso Ijọba Apapọṣe ba ṣe ... wipe lati igbati ... da ... sile ni Iwọ Orun ni nkan ko lọ deede mọ nibẹ. O ... bi nwọn ba da Awolọwọ silẹ awọn Yoruba a ... ri aṣiwaju ti yio ba ... nkan wọ ṣe.

Ọgbẹni Mordi ni ... wipe awọn Yoruba ... lẹ ... o nṣe aṣiwaju ... Dokita Az ... kiwe iṣe alakoso Ijọba Apapọṣe ki o foju anu wo Awolọwọ ki o da a silẹ lati ọgba ẹwọn ti o wa.

Irohin kan ti a tun gbọ lati Urom nibi ipade ... kan ti ... ẹgbẹ Afẹnifẹre (AG) ṣe ... akọni ti ... Oloye Enahoro ... nọ ... orukọ rẹ ni Emmanuel ti ba awọn ọmọ ẹgbẹ ... pa-



Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ

de wọn. Enahoro ni akoko to fun gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ Ọlọpẹ nibikibi ti awọn wa, ki nwọn tun ṣokoto wọn bọ giri, ki nwọn

(Wo iyoku loju ewe kẹjọ)


## LAGOS RACE CLUB

MONDAY 30TH MARCH. SUNDAYS 5TH, 12TH 26TH APRIL & 3RD MAY 1964.

Racing Starts at 3, 30 p. m. each day of the Meeting.

DECLARATION.

Declaration will be made at the Secretary's Office between the hours of 1.30 p.m. and 2 p.m. on racing days.

Admission Ticket/Programme 4/ per day including Entertainment Tax.

Children.

No Children under the age of 14 years will be permitted to enter the Members Enclosure.

Sweepstake.

On each day's race Meeting a Sweepstake will be drawn on the number of Admission Tickets. 1st will be paid £2:10/-, 2nd £1.10/- and 3rd 10/-

Silver Cups

ALSO Two Silver Cups will be presented to the best dressed Ladies in National Costume and Western Dress on the Last day of the meeting.

Special Horses from the North entered for this meeting including four from the Emir of Zaria's Stable. Look forward to BIGGER DIVIDENDS.

# West African Work For Leprosy

LONDON—Doctors and research workers from West and East Africa and from London will tell the story of their work in helping the fight against leprosy anb the latest developments towards stamping out the disease in a special B.B.C radio programme broadcast to many parts of the world in the General Overseas Service with Dr N Fraser, Medical Secretary of the "Mission to Lepers" in London who has recently returned from a visit to East Africa, Dr R G Cochrane, Adviser on Leprosy to the Ministry of Health in London and representatives of Britain's Medical Research Council, where important new work is being done.

Dr S G Brown, Director of the Leprosy Research Unit at Uzuakoli, Eastern Nigeria, will be among those taking part, together

The programme will be broadcast on Tuesday April 14 at 4 15 p.m. and on Wednesday April 15 at 9.45 p.m.




# Britsh Paint Factory In Nigeria

LONDON—A British firm is to build a new paint factory in Nigeria which will help to meet Nigeria's demands for industrial and domestic paints and will eventually produce paints for export to other West African countries.

Pinchin Johnson and Associates, of London (a subsidiary of Courtaulds Limited) will build a factory in Eastern Nigeria at Trans-Amad. The head office will be near to Port Harcourt and production will start in 1965.

'As well as building the faeory,' a spokesman for the firm said recently, 'we shall also train Nigerians to take over key posts at plant. Instruction in technical and administrative matters will be undertaken both in Nigeria and Britain.

Pinchin Johnson have had extensive export connections with Nigeria for many years and the decision to build a factory in Nigeria came as a result of increased demand for paint by industrial users. The new factory will be the first the firm has launched in Africa, and the second outside Britain; one factory has already been built in India

'The founding capital will be £100.000. Initially fifty employees will be recruited though the number will greatly increase in time, 'the firm's spokesman added.

The plant, which is to have the full technical backing of the firm's British factories, will produce 'Gaymel' decorative paints and "Red Hand" marine paints. The factory will be administered under the control of a new company registered in Port Harcourt and named Pinchin Johnson and Associates (West Africa) Limited.



# Ijoba Ila Orun Se Eto Owo Ti Nwon Yio Na

ENUGU—Ni ọsẹ ti o kọja yi ni awọn ikọ ile igbimọ asofin Ijọba Ipinlẹ Ila oru fi okele le owo ti Ijọba na yio nà ninu ọdun yi. gbogbo owo na jẹ £35,571,890. Boya owo na tun le le si laarin ọdun na ko le sọ.

| | £ |
|---|---|
| The Governor | 17370 |
| Premier's Office | 1258130 |
| Audit | 25840 |
| Electora Commission | 268[illegible]0 |
| Judicial | 211740 |
| Legislatur: | 223000 |
| Public Service Commission | 23530 |
| The Ministry of Agriculture | 1599570 |
| The Ministry of Commerce | 283630 |
| The Ministry of Customary Courts and Chieftaincy Affairs | 44100 |
| The Ministry of Economic Planning | 35570 |
| The Ministry of Education | 1370400 |
| Education Grants in Aid | 5884900 |
| The Ministry of Finance | 1367980 |
| Pensions and Gratuites | 117000 |
| The Ministry of Health | 2365170 |
| The Ministry of Information | 369480 |
| The Ministry of Internal Affairs | 419240 |
| The Ministry of Justice | 127480 |
| The Ministry of Local Government | 178270 |
| Grants to Local Government Bodies | 1395500 |

| | £ |
|---|---|
| The Ministry of Town Planning | 281670 |
| The Ministry of Works | 2,470900 |
| Tree Crops: Ministry Schemes | 13.1730 |
| Tree Crops: E.N.D.C. Plantation Schemes | 1600890 |
| Agricultural Training Research and Extension | 39[illegible]850 |
| Animal Health and Husbandry | 104000 |
| Fisheries and Forestry | 50000 |
| Land Use | 75000 |
| Supporting Services for Agriculture | 130000 |
| Trade and Industry | 2436900 |
| Electricity | 60000 |
| Transport | 2309220 |
| Water Supplies | 3187500 |
| Education | 1767750 |
| Health | 377000 |
| Town and Country Planning | 449000 |
| | 70000 |
| Social Welfare | 196500 |
| Public Information | 83790 |
| Justice | 496020 |
| General Government | 1540 |
| Miscellaneous | 200000 |
| Loans Renewals | 153430 |

Apapọ gbogbo owo na jẹ £ 35 571 890

# Eleti Ofe D'araba

# Reluwe Pa Obinrin Alarede Kan Ni Mushin

MUSHIN—Obinrin alarede kan ti orukọ re nję Bosọde Beecroft ni a gbọ wipe ọkọ reluwe pa ni apafọn inu moto ayokele ti o wọ ọgat fẹ re ọja loju irin ni Mushin. Ọjọ idu kan ti o nlọ low paapa wa ninu ẹsẹ kan iku ninu ie awọn alaisan ni Igbobi.

A gbo wipe Shomolu ni Obinrin alarede na n lọ pẹlu awọn toko taya Ọgbẹni J. Adegun at aya rẹ ti o wọ moto won ki nwọn to pade agbako ọkọ reluwe nibiti moto wọn gbe t fẹ re ma kọja.

Eyi ti o jẹ iyalu ni wipe awọn tọkọ taya ti wọn ni moto na, ti nwọn oko si waju rẹ ko fi ara pa rara pẹlu a ọn ọmọde ti nwọn ko lọwọ.

A gbọ wipe ni Olorunsogo ile di bọsi Oshodi ni ṣile na ṣẹ nigbati nwọn ti ibi eku bọ lati Lẹbu Ode ni ọjọ ọsẹ ti o kọja yi.

## Oloye Kan Fi Arugbo Ara Lo Sewon

GBỌKỌ — Adajọ kotu kan tį nwọn sẹṣẹ dasilẹ nį Gbọko ni a gbọ irohin wipe o ju Oloye arugbọ kan sẹwọn ọdun mẹta a ẹni adọrin ọdun ni Oloye na oruko rẹ si nje kovul gagara, Oloye pataki pataki ni jẹ fun awọn ara ilu Jemgbar ni agbegbe Tiv.

Babalawo, Alufa, tabi ẹniti o nṣowo emu

Gẹgebi irohin ti a gbọ Oloye yi pẹlu awọn Oloye meji kan, awọn Tor Donga ati Oloye Gbang a ni adajọ tun-tun na Mallam Bappa Aliyu ni ki nwọn lọ se ọdun meje meje ni ọgba ẹwọn ki nwọn si tun na wọn ni bilala mejila mejila ni idi nitoripe nwọn irofa ati nkan ijamba ninu ile wọn ni akoko ti ọgbọdiyan bẹ silẹ ni arin awọn Tiv.

Adajọ na ni o ṣe nkan itiju lati ri wipe awọn oloye yi ni nwọn wa aidi ji igboro ti awọn pa enia ni ipakupa nayi.

A gbọ wipe ogunna gbongbo ọmọ ẹgbẹ Tarka ni awọn oloye mẹtẹta na.

E ma polowo oja yin, ki e si tun ma ka iwe irohin

ELETI-OFE

ti okun fun irohin aladun losose.

# ELETI-OFE

(A NJU WỌN KO ṢE WI LẸJỌ)

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLE & TELEGRAMME
28, Kosoko Street, Lagos; "ELETI-OFE" LAGOS
P. O. Box 467 Phone 23370

VOL XIV. NO 914 SATURDAY March 28—April 3 1964.


## Oro Olotu

# A Dupe Lowo Gomina Agba

Ọpọlọpọ igba ni a ti ma npa owe yi fun ẹnyin ọkawe wa wipe agbalagba ki wa lọja ki ori ọmọ tuntun wọ. Owe na ti wa tipẹ lati igbati alaiye ti daiye ni, o si nṣe di ọjọ oni fun awọn agbalagba ti o ba moye, ti nwọn ko si nfẹ lati fi agba wọn wọlẹ rara.

Boya ẹnyin ọkawe wa ṣe akiyesi ọrọ rogbodiyan a-o-le-ni-kuro nilu, -ko-ni-le-ni kuro nilu ti awọn ara wa ni Oke Ọya pẹlu awọn arakunrin wa ni Ipinlẹ Ila Orun ni ila awọn Ibo ti nwọn ti mba ara wọn fa.

Ọrọ na kamama, a ko si mọ iru ọmọ ti ọrọ rogbodiyan na le bi, bi ko ba si ti Gomina-agba, Ọlọla Nnamdi Azikwe ti o kesi iọtun tosi wipe ki nwọn fi egun ololo o ọrọ wọn na.

Nwọn ni ilu ti ko ba si ofin, ẹṣẹ ko si:::. Ọlọla Gomina wa na tọka si eyi; o ni lọjọ ti nwọn nfi on jẹ Olori awọn Gomina, o wa ninu ibura ti on bu wipe on a ma fi ọna han awọn ti o ba nṣe alamojuto Ijọba lati ma pa ofin mọ, awọn ko si ni fi iya jẹ ẹnikan lai idi, a i pe ilu Nigera si wa fun ẹnikẹni lati gbe ko ba ṣe Oke Ọya, ko ba ṣe Ila Orun tabi Iwọ Orun. O ni ofin ko gba dukia ẹnikan lọwọ rẹ nipa.

Inu wa dun pupọ lati gbọ iru ikilọ bayi. Amukun ẹru rẹ wọ, o ni lati ilẹ ni o ti wọ wa. O ni kọ ni awọn alamojute Ijọba Oke Ọya ti ntumo ofin ti wọn bi o ba ti wu wọn ti nwọn si nmu u jẹ.

Tani a ri ba wi bigoṣe awa alara.

E Ka Oro Adegbenro ninu Ayiluka
(Loju ewe Karun)

# Iwe Si Olotu

# Sardauna Se Ikilo Fun Awon Ara Re

KADUNA—Ọlọla Ahmadu Bello, olotu Ijọba Ariwa ṣe ikilọ fun gbogbo awọn enia Oke Oya ni ijẹta wipe ki nwọn ṣe mẹlọ mẹlọ nipa rogbodiyan ti o wa larin awọn ati awọn Ibo nisisiyi. O ni Ijọba awọn ko nṣe agba lọwọ meri.

Alhaji Bello ni awọn ko nṣe ẹniti o ngba ile onile lọwọ rẹ. Ni ipade awọn ijoye ati awọn ọba ilu Hausa ni o ti nsọrọ ikilọ yi ni irọlẹ ijẹta nigbati o mba awọn ọba sọrọ.

Ọlọla Alhaji Bello ni Ijọba on mọ ọna ti awọn yio gbe nkan ti o delẹ na gba ti ko ni fi mu ija lọwọ rara. O ni lati igbati a ti gba ominira ni Ijọba on ti nsa agbara lati fi ifẹ han awọn ara Ipinlẹ miran.

O ni loni, bi ẹ ba lọ si ile iṣẹ Ijọba awọn ẹ o ba awọn ajoji nibẹ perẹwu sugbọn o ko le de Ipinlẹ miran nilu Nigeria ki o ba Hausa yẹ ọkan nibi iṣẹ Ijọba wọn.

O ni ko nṣe ibi iṣẹ Ijọba awọn nikan ni awọn fi iye gba awọn ajoji yi, awọn tun faye gba wọn jọja loko ati larin ilu. Ọlọla Bello ni inu iṣẹ diẹ ti awọn fi awọn enia awọn si ni nwọn tun nfi abuku kan awọn wipe awọn ko mọ nkankan ṣe.

O ni awọn Hausa ti nwọn jẹ ọmọ onilẹ ni awọn ajoji yi tun npe ni ajoji nigbati aye ṣo wọn lan. O ni awọn Hausa enia on ki ṣe ẹgbẹ kan rara jẹjẹ wọn kiri.

Ọlọla Ahmadu Bello ni Hausa ko nyọ ẹnikan lẹnu rara.



Alhaji D.S. Adegbenro

# Nihin Lohun Ati Nibi Gbogbo

## Lati Owo Ayiluka

### Odun Ajinde

Nigbati enyin okawe mi ba nkan iwe yi opolopo yin a ti fi omi agbon je ewa fun iranti iya ti Jesu Kirisiti je lodo awon enia re lojo ini Ni oni ojo Sa tide ni a ko kunmo bo Judasi ti o pa Jesu, nitori oje Isinmi a o korin wipe "O JINDE NINU OKU" ni oninla a ti gbagbe gbogbo iya ti Jesu je lori wa, a o yo aso leka.

### Isinku Iya Coker

Oro ajinde iku Jesu Kirisiti ti mo fenu kan yi jeki nmiran isinku nla kan ti emi Ayiluka lo ba won sin ni Sosi ti nwon npe ni African Salem ni Ago Egba ni Ebute Metta ni ose ti o koja yi i Oku Mama Vitoria Jadesola Coker ni mo nso ipa re Bi enia ba wo Sosi naa ri Sosi ti ni lati ri, adura yio si wu e lati gba nibe.

Ko nee ti egan awon Egba ko Sosi sibe; awon omoloku mama Coker ti a Ibe lo sibe paapa fa omo yo lojo a. Ese gbogbo ewon ara Agege, awon Ifake ati ara Abeokuta mo Ibadan ni o pe sibe patapata Be si ni awon omo egbe Afenifere (AG) fi ilu ati ijo dara nibe.

Ninu awon omo egbe Afenifere (AG) na ti nwon wa ba Oloye Kitoye Coker sinku iya re ni Oloye Alhaji D S Adekbenro, igba keji aswaju awon egbe Afenifere ati Oloye O. B. Akin-Olugbade pelu opolopo awon enia ti aye ko si fun mi to lati da oruko.

Mo ki awon omo oloku ati omo omo, awon bi Oluwole ati Aduke wipe ku asehinde. Ehin ya na yio dara.

---

# Awon Ara Kano Le Awon Kan Kuro Loja

KANO— O to egberun enia ti awon Ijoba ibile Kano le kuro loja Sabongeri ni ijeta nitori, o awon fe lo iso won ati pe ati awon ti won nlo iso na ko jeki awon enia ri ona gba rara.

A gbo wipe iwe o kuro nibe ti n on ba fun awon ara oja na fun won ojo meji gbako lati fi palo won mo.

Nwon ni gbogbo awon Ibo ti awon ngae Sokoto, Funtua ati Gusau ni awon ti npalemo wa si Kano ti nwon si nra onje bi eniti o npale ogun mo.

Ni irole ijeta awon asoju marun ni awon omo egbe Ibo ti awon wa ni ilu Kano ran wa si Eko Eko wipe ki nwon wa ba Olola Tafawa Balewa ati Gomina-agba sore nipa iwa ti awon Hausa nhu si a on enia won ni Oke Oya. A ko ti mo bi awon a yori oro na si.




---

# Akiyesi

**A nfe Asoju lati Ilu Okere Ibadan, Oyo, Iseyin, Ondo, ati awon Ilu miran Fun Iwe Irohin Eleti–Ofe**

# E S'ora Lodo Awon Oyinbo Onisowo

### (Lati owo OMO ABATI)

Awọn Yoruba ni nwọn ma np owe wipe "Igi ganganran ma gun mi loju okere ni a ti nkọ ọ" Enyin onişowo, ẹ jọwọ ẹ ṣọra pupọ lọdọ awọn Oyinbo onişowo ti nwọn pọ pupọ kakiri agbaiye nisisiyi. ti nwọn nwa awọn ti nwọn yio pa l'ẹkun kakiri lojojumọ.

Bova ẹ ko 'ile mọ bi awọn ti nşe işẹ jamba wọn na, maa sọ ọna diẹ ti nwọn ngba şe e fun yin ninu iwe irohin "Eleti-Ọfẹ" ti ọsẹ yi.

Awọn Oyinbo nikan kọ ni o nşe işewayo yi, bi o ti wa lọwọ awọn alawọ funfun bẹni o tun kun arin awọn enia-dudu, paapa awọn ọmọ wa niye si yi ti ẹkọ fẹ ba wọn lọr ijẹ

Bayi ni nwọn şe nşe işẹ wayo na : Nwon ti mọ wipe ogunlọgọ enia ni o ṅ wa işẹ wayo na : Nwọn ti mọ wipe ogunlọgọ enia ni nwọn nwa işẹ kakiri ọpọlọpọ ni nwọn si wa ti awọn obi tabi ibatan wọn ni owo lọwọ ti nwọn 'e fi duro fun wọn se işekişẹ ti awọn ba ri.

Nitorina awọn Oniwaye yi a ma iwe-ipolowo oja lẹ sọdọ awọn oniwe irohin nwọn a san owo lati p'olowo wipe awọn ni işẹ pataki kan lọwọ awọn fẹ gba awọn enia si ẹnikan ti o ba fẹ irn işẹ na ki o kọ iwe si awọn ni orukọ adugbo kan.

(Wo yoku loju ewe kẹjọ)

# Atẹsedaiye Omo Enia

(O bere ni ọsẹ ti o kọja ni oju ewe kejọ

2. Oyẹku-Ọmọ ti o ba jẹ alakawaiye odu yi yio jẹ agbẹ laiye tabi ki o jẹ kọle-kọle (Bricklayer) tabi ki o jẹ Olori ọja:
3. Iwori-Ọmọ ti odu ifa ba jẹ alakawaiye rẹ yio jẹ (Printers) tabi ẹniti o nta iwe, tabi ki o ma şişẹ itẹwe (Typist):
4. Idi-Ọmọ ti a ba bi pẹlu Odu yio Joye ọba, minisita, Gevenor, t bi ki o wa aipo Alaşẹ 5. Obara-ọmọ ti o ba ba odu yi waiye, yio jẹ Onişowo tabi ẹniti o ni nkan aşiri lọwọ. 6 Ọkanran-ọmọ ti a ba bi pẹlu odu yi yio jẹ ẹniti o nşe şẹ agbara bi Agbodẹ, işe ẹrọ Moto tabi ki o joye Apena tabi Ayẹgipania. 7. Iresu-ọmọ ti o ba bodu yi waiye, işẹ akọwe tabi oniiwe irohin ni yio şe laiye 8. Ọwọnrin-Ọmọ ti o ba waiye pẹlu Odu yi yio jẹ Dokita Apogun tabi Onişẹ ẹrọ Lẹntiriki. 9. Oguda-Ọmọ ti Odu yi ba tẹle wa saiye yio jẹ jagunjaguu tabi Alapata tabi ọlọşa: 10 Ọsa-Ọmọ ti odu yi ba şiwaju yio jẹ atukọ ofurufu (Pilot) tabi Waya isọrọ.
11. Ika-Ọmọ ti a ba bi pẹlu odu yi yio jẹ Akanọkọ, Onile ere tabi akọrin uigbesi aiye fẹ 12. Oturupọn-Ọmọ ti o ba waiye pẹlu odu yi yio jẹ ọkan ninu ọjọgbọn ile aiye. 13. Irẹtẹ-Ọmọ ti o ba bodu yi waiye yio jẹ Alaro tabi ẹniti o nşe ọti:

(Wo yoku loju ewe kejọ)




PROGRESSIVE BUSINESS GOES FORWARD BY RAIL

If you want to expand your market or industry, you can benefit from the *dependable and low-cost* services and facilities offered by the Nigerian Railway Corporation.

Freight trains on Nigerian Railway Corporation's 1,700-mile system (plus many miles of siding) travel north and south, east and west, all the year round, day and night, providing the vital link of the vast Nigerian Federation. Industries are linked to their markets, produce centres to the ports, little villages to big towns all along the line.

You can count on the thorough co-operation of the Nigerian Railway Corporation at the ports, produce and industrial centres and at any of its 200 and more stations.

And what's more : you are dealing with people you can trust.

SEND YOUR GOODS NATION-WIDE BY RAIL



FOR YOUR RADIO NEXT WEEK

# BBC BOOK REVIEW

## Conflct Of Cultures

"Some time ago," said Ibrahim Tahir in a recent BBC African Service broadcast, I read a book about the pygmies of the equatorial forests of Africa. It was objective and showed a warmth and a loving understanding of the pygmy without any of the starry eyed sentimentality or the condescension that sometimes affects the writing of many European writers of African peoples."

Now theauthor of that book, Colin Turnbull, had written another book called "The Lonely African," and Ibrahim Tahir reviewed in the BBC African Service programme A BOOK FOR TODAY. "The loneliness of the African which concerns Mr. Turnbull," he said, "is that produced by alienation from the traditional way of life through contact with European ways and education, and rejection by the very white man who has sought to stamp the African with a European image."

The author chose a number of individuals from various parts of Africa, each in conflict with different aspect of this problem. There was the servant Mosuidi, a Northern Rhodesian, whose European master sent him to a mission school and made a clerk of him. When Masoudi retured to his tribe with his new way, they were all suspicious of him, and finding a wife proved impossible. There were the old chiefs who found that the younger generation would not respond to the old loyalties. There were the politicians and educated civil servants who worked according to new principles and new ideas, but found that in both private and public life the old traditions and values exercised disconcerting influences.

(Cont'd on page eight)

# BBC NEXT WEEK

Following are the programmes in the BBC African Service during the coming week, to be broadcast after the NEWS 1[?]00 GMT on 17.81 and 21.615 megacycle in the 16 and 13 metre bands:

| | |
|---|---|
| Sunday, April 5 | Loud n Fanf r: |
| Monday, April 6 | A Book For Today, Focus On Africa, In Perspective, For You At Home |
| Tuesday, April 7 | A Book For Today, Postmark Africa, African Mirror, Calling Ghana |
| Wednesday, April 8 | A Book For Today, Focus On Africa, freeau Forum |
| Thursday, April 9 | A Book For Today, Focus On Africa Discussion Calling Nigeria |
| Friday, April 10 | A Book For Today, Focus On Africa, World Horizons Writers' Club |
| Saturday, April 11 | Sh[?] time For Parents And Teachers, Calling Sierra Leone |



Ipa Keji Irin Ajo Olola Tafawa Balewa
S/ Ipinle Iwo Orun Apa Keji

## Esora Lode Awon Oyinbo Onisowo Wayo

(O bere loju ewe kefa)

Ti o ba de ibe, iwo ko nigri ile-ise kan rara nibe, awon ti o tile ngbe ile na a se wipe awon ko mo oruko onise paapa ti o wa bere lodo awon.

Kini o ti ri ile ohun papa si? Boya ile ti awon arugbo tabi awon obinrin oloja ngbe ni. Awon oniwayo na a fi eyi se iboju wipe ki nwon ma fi iwe iwa'se ti nwon ba nko si awon sibe.

Li odun ti o koja yi' opolopo enia ni awon oniwayo yi fi iru ona bayi palekun. Okan niyi:

Ogbeni kan ni ilu okere ti o nwa ise, ri ikede nla kan ka ninu iwe irohin kan l'Eko wipe awon kan nile eniti o ba le se ise akowe, nitoripe aye sisile fun enia marun lodo awon Ni iseju-akan, ogbeni na si ti kowe si won wipe ki won gba on si ibi-ise won na;

Ogbeni na tu'le jo-tona jo, o fi owo na ranse si won, sugbon ise na ko te e lowo d'ojo oni.

Enikeji ni ogbeni onisowo kan Ipinle Ila-Orun ti awon Oyinbo onisowo oniwayo kan kowe si lati ilu India wipe ki o fi owo sowo si awon nitoripe awon ni awon ojakan nile fun tita ni kika.

Onisowo Ibo na fi owo sowe, sugbon titi di ojo oni, ko si oja kan ti owen fi sowo sii;

Nitorina, e s'ora nyin; enyin onisowo wa lode awon Oyinbo oniwayo.

## Oselu Kan Bebe Wipe Ki Nwon Da Oloye Obafemi Awolowo Sile

(O bere loju ewe kinni)

duro sinsin si idi otito ti nwon wa.

O ni irohin rere won ti awon asiwaju w n ti o'wa lewon ba ngbo wipe nwon duro sinsin ni yio ma se awon na lokan giri ninu ogba ewon ti nwon wa. Enahoro ni ko ye ki awon omo Egbe Olope (AG) so ireti nu rara nitoripe opolopo awon asiwaju egbe won ti ba igbi lo. O ni nitoto kise gbogbo awon ti nwon ba lo soju ogun ni nwon npada bo wa sile; O ni o ye ki awon omo egbe Afenifere yi mo wipe 'oju ogun ni olukuluku won wa nisisiyi, ki nwon si se ara giri, ki nwon le la ogun na je.

## Atesedaiye Omo Enia

(O bere loju ewe kefa)

14. Otura-Omo ti a ba bi pelu odu yi, yio gboye giga laiye tabi ki o je adeja tabi ki o je Loya 15. Ose Omo ti a ba bi pelu odu yi yio je Olorisa tabi Elemi-mimo tabi eniti eniti egun-agun, tabi ki o da ijo sile. 16. Ofun-Omo ti a ba bi pelu odu yi yio je Adajo, Olopa Babalawo, Alufa, tabi entii o nsowo emu.

---

## Nwon Yo Kola Balogun Loye

IBADAN

Oloye Kola Balogun ti nwon fi je oye JAGUN ni Otan Aiyegbaju ni aipe yi ni a gbo wipe nwon gba oye na lowo re lana.

---

Ayiluka Ki:

## Awon Ero Meka

Gegebi mo ti so fun yin ni aipe yi wipe opolopo awon gbajumo Eko ni nwon nlo si Meka lodun ni mo gbo wipe awon ero ti nwon nlo si po pupoju sugbon awon ara Eko ti o nlo lodun ni pe leke; Bi awon odomode ti nlo ni awon agbalagba paapa ni o okunrin ati lobinrin; mo gbo wipe obinrin wa kan ti a npe ni AUNTI IGA ni IGA KOSOKO nlo, o si tun mu obinrin kan lo pelu.

### Alhaji Ibo

Mo gbo wipe olori awon egbe Imale ilu Ibo, Alhaji Sayidi Ibrahim ti o je eni akoko ti o koko lo si Meka ati Medina tun nlo ni odun ni ati pe nigbati o ndagbere fun awon omo egbe re ni Afikpo ni ijeta, o ni adura ni ebo Imale, o ye ki gbogbo won dorikodo ki nwon gbadura fun ilu Nigeria ki ija igboro mo le da ilu si meji Alhaji ni nu ko toro rara.

Oro re o enyin ero Meka, ile ni a ti nkeso lo sode. Bi e ba gbadura fun wa tile tan ki e tun gbadura fun wa ni oke Arafa.

### Ona Ofun

Mo gbo wipe awon oba Yoruba mejila ti nwon sare lo si Ibadan ni ijeta lo yanju ara won nipa oro awon oselu ni nwipe ona ofun ni ona orun. Nwon ni awon ti nse egbe oselu kan rara sugbon alatilehin Ijoba ni awon nse nigbakugba ki nkan ma baje.




Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company, 28, Kosoko Street, Lagos, Phone 23370 Editor (Olotu) Ola Onatade, 15, Kosoko Street, Lagos, P O Box 467,